Àwọn èròjà erùpẹ̀ ilẹ̀ tí a lè fojú rí- Ìdánrawò P01

# ṢÍṢE ÌDÁMỌ̀ ORÍṢI ERÙPẸ̀- Lílo Ohun èèlò Olórùka

Awòrán atọ́ka *n. 4-7a-8a*

## ÌWÚLÒ

Oríṣi erùpẹ̀ wà lọ́wọ́ irúfẹ́ àti iye erojà tó wà nínú erùpẹ̀ ilẹ̀ bí àpẹẹrẹ, iyanrìn, amọ̀. Oríṣi erùpẹ̀ ni o máa n sọ bí omi ṣe pọ̀ sí nínú erùpẹ̀, bí atẹ́gùn ṣe wà sí, àti bí àwọn èròjà inú erùpẹ̀ ṣe wà sí. Tí a bá mọ irú erùpẹ̀, a ó ní ànfààní láti ṣe àyẹ̀wo bí omi ṣe pọ̀ tó níbẹ̀. A tún lè fi ọwọ́ mọ bí erùpẹ̀ ṣe rí nípa títẹ erùpẹ̀ wọ̀rọ̀kọ̀

## ÀWỌN IRINṢẸ




Ohun èèlò ìbule




Omi

## ÌGBÉSẸ̀ IṢẸ́

1) Fi ohun èèlò ìbulẹ̀ bu ìwọ̀nba erùpẹ̀ díẹ̀, kí o wọ́n omi sí i.




2) Ṣu erùpẹ̀ náà róbó róbó ní ìwọn sẹ̀ntimítà mẹ́ta. Ṣe erùpẹ̀ náà ṣe é ṣù róbó róbó? Tí kò bá ṣe é ṣù róbó róbó, iyanrìn ni erùpẹ̀ náà. Tí o bá ṣe é ṣù róbó róbó, má a bá iṣẹ rẹ lọ..





3) Tí erùpẹ̀ tí o ṣù pọ̀ bá tú ká, ó jẹ́ iyanrìn(tí kò kúná)

4) Fi erùpẹ̀ ṣe goro tó ga ní ìwọ̀n sẹ̀ntimítà mẹ́fà, tí erùpẹ̀ náà bá túká, , erùpẹ̀ ọlọ́ra oniyanrìn (tí kò kúná) ni.

5) Jẹ́ kí goro náà ga ní ìwọ̀n sẹ̀ntimítà mẹ́ẹ̀dógún, tí erùpẹ̀ náà bá túká, , erùpẹ̀ ọlọ́ra oniyanrìn (tí kò kúná) ni.

6) u erùpẹ̀ kí ó tẹ̀ kọrọdọ. Tí ó bá túká, Ṣerùpẹ̀ ọlọ́rà ni (tó kúná níwọ̀nba)

7) ) Fi erùpẹ̀ ṣe òrùka tó wà ní ìwọn sẹ̀ntimítà mẹ́ta. Tí ó bá túká, erùpẹ̀ oníyanrìn tó ní amọ̀ díẹ̀ ni (tó kúná níwọ̀nba). Tó bá là, erùpẹ̀ ọlọ́rà tó ní amọ̀ ni (tó kúná dáadáa). Tí orùka náà bá dúró dáadáa tàbí tó fọ díẹ̀, amọ̀ ni (tó kúná dáadáa).



| | |
|---|---|
| ÀWỌN ÀNFÀÀNÍ TÓ WÀ NÍNÚ ỌNÀ TÍ A GBÀ ṢE ISẸ́ YÌÍ | nà àyẹ̀wò tí a lè fojú rí, láì lo àwọn irínṣe Kankan. A lè lo irú Ọ̀nà àyẹ̀wò yìí ní gbogbo agbègbè àti fún gbogbo oríṣI erùpẹ̀. |
| IBI TÍ ỌNÀ TÍ A GBÀ ṢE ISẸ́ YÌÍ KÙ SÍ | - O ṣe é ṣe ká nílò ìdánilẹ́kọ̀ọ́ nípa bí a ṣe le fi ọwọ́ dá oríṣi erùpẹ̀ mọ̀ àti bí a ṣe lè ṣe goro. Kò rọrùn láti mọ iye ìwọ̀n tí ẹgbẹ́ kọ̀ọ̀kan jẹ́. |
| ÀWỌN IBÉÈRÈ TÓ YẸ KÁ DÁHÙN | - Njẹ́ o ṣe é ṣe láti fi ọwọ́ dá oríṣi erùpẹ̀ mọ̀?<br>- Njẹ́ o ṣe é ṣe láti ṣe goro?<br>- Báwo ni goro náà ṣe gùn tó?<br>- Báwo la ṣe rò pé ṣíṣàn kúro omi àti mímú kí èròja erùpẹ̀ dúro gíri yóò ṣe yàtọ̀ láàrin iyanrìn àti amọ̀? |

## ÀPẸẸRẸ ÀBÁJÁDE ÀGBÉYẸ̀WÒ

| Adàpọ̀ erùpẹ̀ ọlọ́ra, iyanrìn àti amọ̀ | Kò dára tó | Ó dára |
|---|---|---|
| Àwọn èròjà iyanrìn wa nínú erùpẹ̀. Irú àwọn erùpẹ̀ bẹ́ẹ̀ máa n gbẹ, èròjà inú wọn kì í dára tó bẹ́ẹ̀. Omi tètè má a n ṣan kúrò lára wọn. | Erùpẹ̀ yìí jẹ́ àdàpọ̀ iyanrìn àti erùpẹ̀ tó kúná | Erùpẹ̀ náà kúná dáadáa, o sì lẹ̀. Irúgbin a ṣe damadáa níbẹ̀. Ó fààyè gba àwọn èròja inú ilẹ̀. Ṣùgbọ́n àwọn apá kan níbẹ̀ lè jẹ́ erùpẹ̀ líle. |

| KÒ DÁRA | Ó DÁRA NÍWỌ̀NBA | Ó DÁRA |
|---|---|---|
| Àwọn èròjà erùpẹ kò jẹ́ kó wúlò púpọ̀. Iyanrìn ibẹ̀ lè pọ̀ jú kí ó má lè gba omi dúró tàbí kó kúná ju. Kó ma ṣe é ro.. | Erùpẹ̀ dára. Kò sí ìdíwọ fún ìtàkùn láti gbèrú. Ààyè wà fún omi àti atẹ́gùn.. | Erùpẹ̀ náà kúná dáadáa, o sì lẹ̀. Irúgbin a ṣe dáadáa níbẹ̀. Ó fààyè gba àwọn èròja inú ilẹ̀. Kò ṣe ìdíwọ fún ìtàkùn láti gbèrú. |